# IROHIN IMỌLẸ

MỌLE ORE AIYE TẸNI GBOGBO LAWA

NO 1,705 WEDNSDAY FEBRUARY 23, 1966 (3d)


## Ina Jo Enia Meji Pa Sinu Ile !

KANO:— Ọrọ di bi o lọ o yago fun mi nigbati Ijamba ina nla kan ṣẹlẹ ni agbegbe Kano ni opin ọsẹ ti o kọja lọ yi eyiti awọn obinrin arugbo meji kan si jona ninu ile nigbati ina nla na ṣẹlẹ eyiti awọn obinrin na si jẹ ẹni ọgọrin ati adọrin ọdun ti awọn eru eyiti o to ẹgbẹwa pọnun (£2,000) si jona sinu ina nla to ṣẹlẹ na.

Irohin fi ye wa pe ni ilu meji ni ijamba ina na ti ṣẹlẹ eyiti awọn obinrin arug o meji si ku sinu ina nla na.

Ninu irohin to de ọwọ wa lati ilu Sumalia fi ye wa pe ina nla na ṣẹlẹ ninu ahere arugbo obinrin ti iṣe ẹni ọgọrin ọdun ti o si jo obinrin na to ku sinu ina na ni abuleko kan ti nwọn npe ni Kafin lafia.

Bakanna ni irohin tun fi ye wa pe obinrin arugbo keji ti nwọn npe niHabma ti iṣe ẹni adọrin ọdun si kagbako ku tirẹ ninu ijamba ina nla kan to ṣẹlẹ nii ile ibiti nwọn ti nṣe onjẹ ni abuleko kan ti nwọn npe ni Jahun ni ẹsun Kano.

Oniwe irohin wa ni ilu Kano fi ye wa pe awọn ile ti o jona rau-rau sinu ina nla to ṣẹlẹ na jẹ ọgbọn ati pe ọkẹaimoye awọn ohun ọsin, onjẹ to jẹ pe o jona sinu ijamba ina nla to ṣẹlẹ ninu awọn abuleko meji na.

# IJỌBA FI ẸSUN OLE KAN MINISTA MARUN

IBADAN: Gbogbo ile ẹjọ kekere ti ilu Ibadan lo kun sọsọ ti ṣsẹ ko gbero fun ogunlogọ okẹ aimoye enia ti wa sile ẹjọ na ati pe gbogbo awọn enia na l dakẹ jẹ jẹ bi ewe ogẹdẹ ti nwọn si tun ya ẹnu s lẹ nigbati ile ẹjọ kekere na bẹrẹ ise ọjọ na eyiti nwọn pe awọn Minisita marun ti Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria tele ti nwọn ka ẹsun si ile ẹjọ na si kan wọn pe nwọn jale Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun ati pe iye owo ti awọn Minista marun na ji si jẹ ẹgbaa okẹ meta ati ẹgba pọnun (£62,000) ti iṣe owo Ijọba Ipinle na eyi ti ẹgbẹ Demọ se akoso re koja ki Ijọba Ologun to gba eto akoso Ijọba na.

Awọn minista marun ti Ijọba Ologun Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria nba ṣe ẹjọ lori ẹsun ole ati pe awọn Minista na ji owo Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun gbe na ni Ọgbẹni J. O. Oshuntokun Ọgbẹni D K Olumofin, Alhaji Z A Opalẹyẹ Ọgbẹni Bandele Bello ati Ọgbẹni Sura S nni

Oniwe irohin wa ka ran wa leti pe ninu ọsẹ to koja lọ ni awọn olọpa nu lo mu Alhaji Z A Opalẹyẹ si lati Ilọrin nibiti o lọ ṣe ati po si eyiti awọn ọlọpanu na si mu padabọ si ilu Ibadan lori ẹsun ti ti awọn Ọlọpanu na ko sọ fun oniwe irohin wa nigbati o fi ọrọ nwa wọu lẹnu wo lẹsẹkẹsẹ ti ti nwọn mu Alhaji na de si ilu Ibadan ni ọjọ na

Bakanna ni Oniwe irohin wa to wa ni Ilọrin tun ran wa leti pe ni akau bi ọsẹ mẹta sẹhin ni Alhaji na sọ ni ilu Ilọrin nibi ti o lọ sa pamọ si pe on ko ti awọn iyawo on ati awọn ọmọ ọmọ on pẹlu. Alhaji Z. A. Ọpalẹyẹ tun ṣe alaye fun oniwe irohin wa lasiko na pe ki on to sa wa si Ilorin lati wa daabo bo ẹmi awọn enia kan ti pa awọn enia meji kan to nsọ ni lasiko ti rogbodiyan fi bẹ silẹ ni Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria lori abayori idibo si Ile Igbimọ Aṣofin Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria ni ọjọ kokanla oṣu kẹwa odun to koja lo yi.

Oniwe irohin wa kan tun ran wa leti pe bakanna ni Ọgbẹni Joseph Oshuntokun ti o ti fi igbakan jẹ Minista Alamojuto eto ẹkọ fun Ijọba ti ẹgbẹ ṣe eto a o so rẹ ni Ipinlẹ Iwọ Orun koja yi lọ mu ninu ile rẹ ni Ibadan eniti Ọgbẹni J. A. Adeyi ti o jẹ Minista

WO OJU EWE KẸFA

# Nwọn Fẹ Ta Ilẹ Akintọla ni Gbanjo

IBADAN:— Ninu irohin kan to de owo wa ni ọjọ Isẹgun ti iṣe ọjọ kejilelogun oṣu yi ni a ti gbọ pe Ile Iṣẹ kan ti oma nta oja gbanju ti wọn npe ni "Ailaye Akuola Liceced Anctioneer Valuer and Estate Agent" ti se Ikede pe ile iṣẹ fẹ ta awọn ilẹ kan ile ṣe to nta ọja goanjo na ti ṣe ikede fungnogbo aiye gbọ lat mọ boya nwọn yio ri enia yio ra ilẹ na ni gbanjo.

Ninu irohin to de ile Iṣẹ wa ni oniwe irohin wa ni ilu Ibadan fi ye wa pe ile iṣẹ to nta ọja gbanjo ti polowo sinu awọn iwe irohin lati mọ awọn eniti o ba nfẹ ile lati ra ati pe ile Iṣẹ to nta ọja gbanjo na ti ṣe gbogbo alaye lori ile Akintola ati awọn ẹbi rẹ na ti nwọn fẹ ta na.

Irohin fi ye wa pe ninu awọn iwe irohin ti nwọn ṣe ipolowo ọja na si ni ile iṣẹ to nta oja gbanjo na ti ṣe alaye ibiti ile ti nwọn yio ta na wa eyiti o ṣe alaye pe ilẹ na si wa ni Ọsakoko lati lọ si ori le iyana Ibadan si ona Ijẹbu—Ode ati ilẹ na si jẹ 70,494 acres gẹgẹbi ilẹ ti nwọn fẹ ta ni gbanjo na ti ṣe tobi to.



Ologbe S. L. Akintọla

# NJẸ IWỌ MỌ ẸNITI ỌLỌRUN IṢE ?

Ibere ki Ibere ni o ma ti ọkan ọmọ enia wa nigbati ọwọ ba dilẹ ti ko ba si ẹniti o nyọ lẹnu tabi ti wahala kekere ati nla ba wa lọna rẹ. Tabi ọkan enia ba poruru ti ko mọ ọna ti yio gba. Lẹhin eyi to ba gbadura titi ti ko ba tete ri idahun awọn Ibere rẹ. Enia a ma ṣe awari ninu ọkan rẹ pe nibo ni Ọlọrun wa ? Kini ṣe ti Ọlọrun ko gbọ adura mi ?

Nibo ni Ọlọrun na wa ? Elomiran a dilẹ ma sọ pe Ọlọrun ti gbagbe on. Irẹ awọn Ibere bayi ni o ma saba wa ninu ọkan ọmọ enia.

Ohun to han gbangba ni pe ẹnikeni ti o ba ti bere ohunkohun lọwọ Ọlọrun Oluwa rẹ ti gba pe Ọlọrun ju on lọ ati pe Oluwa re ti gba wipe Ọlọrun lo ranidi ohun gbogbo ju on lo.

Lori ero yi ni mo fẹ sọrọ le lori loni la bere ninu ọkan mi pe, Tani Ọlọrun iṣe ?

## Ruṣu - Ruṣu

Nigbati mo wa lomode ti mo ba wo o j u sauma lasiko ti orun nwo lọ ti mo wa ri oju orun to p u p a ruṣuruṣu emi a ro lọkan mi pe Ọlọrun farahan mi ninu ọla Rẹ nla

Nigba miran awọn ibi to pupa ruṣuruṣu wọnyi ada-bi ẹn pe awọn ori enia fa-rahan kakari ninu awọ sanma, Ninu awọn to ba to-bi to saumа,

Emi a ma ro pe ori awọn Ọba nla ti o ti kọja le fara-han mi. Iru awọn ero bayi ni o wa ninu ọkan mi ni-gba ewe mi. Nitori na mo ni ifẹ lati ma ṣe awari ẹni ti Ọlọrun ṣe pupọ,

Awọn Obi a ma ba mi wipe ese ti mo fẹran ati ma da joko lati ma wo oju ọrun nikan nigbagbogbo? Bo tilẹ jẹ wipe awọn Obi mi ba mi wi pe ese ti mo fẹran iwa bẹ ṣugbọn emi ko ni salai ma wo oju ọrun kinsi ni ayọ kikun lori awari mi yi,

Ṣugbọn lẹhin ti mo wa-di ọmọ lẹhin Jesu ti mo si ngbọ ọrọ awọn Oniwasu ero igba ewe mi nd'nku ni ẹdiẹ titi emi fi rẹ gbagbe iwa ewe mi to ṣe iyebiye fun mi.

## Rossia

Ṣugbọn ibere yi diuku rara lọkan mi lati ma bere wipe, Tani Ọlọrun yi se? Emi si mọ wipe opọ ni yio ma ni iru iwa yi lọkan wọn pe tani Ọlọrun yi ṣe ?

Awọn miran wadi titi ẹniti Ọlọrun ṣe ṣugbati ṣugbọn nigbati ogbọn ati imọ wọn dopin Nwọn bere o si sọ pe Ọlọrun kan ko si nibi kan.

Iru awọn enia be ni Oga gun Russia kan to wipe ko si Ọlọruu, Ṣugbọn ni-gbati on ati ọmọ rẹ wa lo-ju ogun kan pọ lairotẹlẹ ọta ibọn ba ọmọ bibi inu rẹ to subu lule ṣugbọn lai-ro tẹlẹ igba ojiji jade lẹnu Ọgagun yi pe Ah Ah Ọlọ-run mi

Ṣugbọn ọmọ Ogun keke re kan to wa legbẹ Ọgagun yi dahun pe Olori Ogagun mi ọwọn ṣe ẹnyin mo pe ko si Ọlọrun? Kini o tun mu nyin lati ma ke pe Olo run? Lẹsẹkanna ni Ọgagun yi wa ọmọ ogun kekere yi pe mo gbo bayi pe Olo run wa nibi kan.

Bayi opolopọ nṣe agbara agabagebe pe ko si Ọlorun ṣugbon ninu inira won, ke gbe pe Ọlorun, Ọlorun si da won lohun ninu iponju won gbogbo.

Laipẹ yi ni awon orilẹede meji ndije ati de ibiti oṣupa wa, awon mejeji na ni Ru-ssia ati America lakoko ni gbati Russia sumo Oṣupa o so fun araiye pe nigbati on de oke lohun gbogbo oju orun dara wo

O si lo titi ati papa on ko gburo Ọlorun ko gburo Ọlorun tabi ki on gbo ohun iro Orun ati papa ko si Ọlo run lohun ni

Nigbati omo ilẹ America de oke lohun ni ibiti oṣupa wa o so fun araye pe bi on ti nlo soke lohun ni beni ewa Ọlorun nfi ara han on titi o wa so fun araiyẹ pe daju Ọlorun tobi pupo ati pe Ọlorun wa nibi kan

Nitori gbogbo nkan ti en ba pade ti on si ri wonyi ko le da ara won bikoṣe pe ẹni kan ba wa ti o si da won

Nitorina ẹnyin ko ha ri otito to wa ninu awon enia meji yi? Bi nkan ba wa pe alagbara ẹni ti la fi eri fun Ọlorun tabi la juba Ọlọrun njẹ ẹnyin ko ha ri awọn iyonu nla to de ba won lode oni

## IGBERAGA

Ọba Nebukaninissari fẹ rẹ ni gbogbo aiye nigba ti giberaga pe owo on lo on fi ko ilu Babyloni laisọ pe Ọlorun to fun on lowo lati ko ṣugbon fun idi eyi a so di eniti tojẹ oko bi malu ti ti di igba meje fi koja lori rẹ.

A tun gbọ itan Napoleon Ologun nlani Ọgagun yi nṣe ẹniti Ọkorin nfi bura ninu ogun, Ṣugbọn ninu ọna rẹ o gbati ko fori ba-lẹ fun Ọlọrun o sọ di ẹni igbagbọ.

Laipẹ yi a tun gbọ oru-ko Ologun nla kan lati Ile Germani Adolfu Hitler ko juba Ọlorun to ninu ogun iṣe lẹni a tun ṣe?

Lati Owo

di ẹni Itan ati ẹniti a gba-gbe sinu aginjo aiye Bebe lo ni ao ma ka awọn a iru awọn ẹnibe lo, Ṣugbọn ki ni ero tirẹ ati e ni na papa

Mo tun bere lọwọ rẹ pe



S. O. JAIYE

Tani Ọlọrun? Idahun tem i nipe Mo Olọrun pe on ni Orisun ohun gbogbo to de ohun gbogbo ti o npese on na gbogbo fun ẹda,

Oba elesan gbogbo ni iṣe yala ibi lọmọ hun ni ya la rere lọ mọ ṣe ni Olorun ni eleṣan gbogbo nkan Bi oti pe ara Rẹ ni Olọrun ẹsan bẹni o pe Ara Rẹ ni Olorun Ife Bi Olorun ti jẹ ẹni Ire bẹẹni o jẹ ẹni Ipa-ri wa

Nitori na lodo rẹ nigbe ri ati iwa laiye wa ti bere Lọd. Rẹ ni ao si pari Igbe si aiye wa gbogbo yala no pe ni tabi ko pẹ

Ju gbogbo rẹ lo mo wa gba Olorun pe ẹniti gbo-gbo ẹda ni lati ma juba ti aiye a nipẹkun Iwọ ṣi o nwa Olọrun kiri mo jẹri si pe ai ye to de be ti yio tun pada bo mo

Nitori na mo Olọrun ni nu Emi o titọ ni osi ma sin lotitọ ati lododo M ṣe wa di Ọlọrun mo l k o k o ko le wadi mọọ to

O Di gboṣe ar m

## AKIYESI PATAKI

Eleyi ni lati sọ fun ẹnyin onkawe wa jakejado Agbaiye pe ni agbara Olodumare laipẹ lọjọ iwe wa IRO IN IMỌLẸ, yio di araba eyi ni pe yio tobi pupọ ju ti Isisiyi

Awọn orisirisi nkan wọnyi ni ẹo si tun ma ri ka ninu re, Irohin Aladun kakiri Agbaiye, Itan arikọgbọn, owe, Alo ati itumọ, Irohin kayefi, ọro awada ti o pani lerin lati enu Yeye natu oniyeye Eko ati Baba Alawada Ọyọ. Awọn ohunti yio sele si ẹ lọọjọ, orisirisi aworan ti yio han rekete, nibi igbeyawo, ikomo jade, ojo'bi, oku ojo oja ile wa ati awon nkan miran ti o magbadun ju ti Isisiyi lo

Nitorina a ki ny'n ku ifoju sọna

OLOTU

## Iwe si Olotu Irohin Imole

### Ijoba Ko Ranti Ilu Olorunjare

OLOTU:- Nba ọpẹ bi ẹba le gba mi ni aye ranpẹ ninu iwe yin oloyin momo lati kesi Ijọba Ipinlẹ Ariwa ile Naijiria lati lo ipo re rere ki nwọn le ba wa tun awọn oju ọna ilu Olorunjare ṣe ni asiko.

Lati ọdun pipẹ ni Ijọba Ipinlẹ Ariwa koti ya si ilu wa rara ti nwọn si ntan awọn ilu miran papa awọn ilu ti ko tobi to ilu wa Bẹ si ilu Olorunjare ko kere rara ninu awọn ilu ti o wa ni Ipinlẹ na si yatọ pupọ si awọn ni Ipinlẹ Ariwa ilẹ Naijiria.

Bi enia ba rin oju ọna na, olu ware yio ri pe, ko dara to, o ti bajẹ fun rinrin o tun lewu pupọ awọn onimoto tabi rin ẹsẹ.

Inu wa yio dun pupọ bi Ijọba Ariwa bale ṣe aanu wa lati tete mu oju to oju ọna na ni asiko.

Olotu mo dupẹ fun yin ti ẹgba mi laye.

Emi ni
R. O. Adisa
OLORUNJARE

### Idahun Si Oro Ogbẹni Dunmoye

Olotu jọwọ gba mi ni aye diẹ ninu iwe nyin to kun fun ogbọn ati oye lati fun Ogbẹni Dunmoye ni idahun ọrọ rẹ ti o jade ni ọjọ kẹwa oṣu yi eyiti o sọ pe Jesu ki iṣe ọmọ Olorun eyi si jẹ ohunti o ya mi lẹnu fun Ogbẹni na.

Mo si fẹ fun Ogbẹni Dunmoye ni ẹri pupọ ninu Iwe Mimọ Bibeli ki o si lọ wo Maku Ori Kini ẹse Kini ati Matteu Ori Kerinla ẹse Ketalelogbon Matteu Ori 3 ẹse 17 ati Luku Ori Kini ẹse 35, Angeli na si sọ pe ẹmi mimọ yio tọọ wa ati agba ra ọga ogo yio ṣiji bo ọ nitorina ohun mimọ ti oti inu rẹ bi ọmọ Galatia Ori Kerin ẹse Kini nitori na mo fẹ ki Ogbẹni Dunmoye lọ ka wọn daada.

Eleyi yio fi ye pe ọmọ Olorun ni Jesu iṣe bi oba ti ri ibiti Jesu ki iṣe ọmọ Olorun ki o jẹki a mọ kio si fun wa lesi eleyi ki emi na fun fun ni awọn ẹri miran.

Olotu ẹ ṣe pupọ fun aye ti ẹ gba mi ajinde yio ma jẹ fun nyin ọkọ Ọba ko ni ṣa nyin lẹsẹ ẹ ko ni si awọn ọrọ na tẹ o.

Emi ni
J. A. Enijanla
EṢ'Ẹ

### A Nfẹ Aworan Baba Eṣo

Olotu/ Inu mi yio dun bi ẹ ba le gba mi ni aye diẹ ninu iwe nyin to kun fun ogbọn ati o y e lati kesi Ogbẹni Eṣọ ti a ma nri itan eyiti o jẹ ti igba lailai ka lati ọwọ rẹ ki o jẹki ari aworan rẹ ninu iwe Irohin Imọlẹ nigbati aba ti ri itan Ogbẹni Eṣọ ka.

Mo ro pe o to ẹ mẹta ti awọn Onkawe Irohin Imọlẹ ti ma nkọ ọrọ nipa ti Aworan Ogbẹni Eṣọ eyiti nwọn ma nbere pe awọn fẹ ri aworan rẹ ninu Iwe itan t' o ba sọ sinu iwe Irohin Imọlẹ.

Inu awa onkawe Irohin Imọlẹ yio dun bi Olotu Iwe Irohin Imọlẹ ba le ba wa sọ fun Ogbeni Eṣọ ki o jẹki a tete ri aworan rẹ ninu iwe Irohin Imọlẹ eyiti a ti nfẹ ri lati nkan bi oṣu diẹ sẹhin.

Mo dupẹ pupọ Olotu fun a y e ti ẹ gba mi ọkọ ọba ko ni ṣa nyin lẹsẹ o ajinde yio ma jẹ fun nyin o.

Emi ni
James Adelana
Apapa Ajegunle


BEREFUN OJULOWO EGBOGI—

## "Congreve's Iodo Form—Oinment



Atamatase ni egbogi" ADI-BLEGBO" yi j- fun itọju gbo gbo orisirisi "EGBO—ESẸ" ni kiakia bi o ti wu ki jọ rẹ ti le pẹ t'. Adielegbo yi ko ni egbẹ ojia wipe awa ko idọti ni bi ẹr gbogbo ti ba wa loja egbo patapata jade oju re yio si mo daradara. Lẹhinna oju egbo yi o sa jin sinu yio jẹki oju rẹ hu wa soke, yio si pọn daradara tun bakanna ko ni mọ werewere ni yio si san patapata Alafia de si ọ niyen!

Ri daju gbangba wipe awon sobu ti a da oruko won ahasale iwe yi ni ogbe ranṣe lọ ra. Bibeko awon Ele ihin on ibiti yio ta 'Adamodi' re fun o maṣe gba rara

Waterloo Medecine Stores
9, Palm Church Street P. O Box 333 Lagos



## Kini O Mu E Ronu Nipa Awọn Aṣọ Rẹ ?

Bi o ba ni aṣọ fun fifo tabi lilo ni aṣọ bi owu (woolen) tap.ts, aṣọ oke, Guluea Brocade ni ti Ọkunrin tabi ti Obinrin. A ni orisirisi aṣọ ti o ba ni fun fifo tabi ti o ba fẹ yi awo ara aṣọ na pada si orisi awọ miran ti o ba fẹ. (Changing of Colours)

*Tete Gbe Wa Si Ọdọ*

### Iwajowa Cleaner Enterprises
87, ỌDUNFA ST, Phone 20029 Lagos

Kia ni ao ba ọ fọ, ti iwọ yio si ri gba ni sẹ kanna, O le ranṣẹ si wa ki a wa ko awọn aṣọ rẹ na tabi ki o pe wa lori ẹ r ọ isọrọ (telifonu) ti nọmba rẹ wa loke wa yi.

Bakanna ni a si tun nba enia gbọn ile rẹ nu tabi bi o ba si fẹ kun ile tabi ile iṣẹ rẹ, iṣẹ wa tun ni yẹn na Bi enia ba si fẹ kọ ile tabi o ṣẹṣẹ kọ tan o si fẹ kun o le gbe fun wa ki a ba kun, ki a si ba ṣe lọṣọ ti yio jẹ oju ni gbese, A ni gbogbo iṣẹ ti o ba ti jẹ ki a t u n nkan ṣe ni o nṣe iṣẹ tiwa.

Dan wa wo lẹkanṣoṣo ki o si ri bi iṣẹ wa ti dara to. Owo pọku ni a si ngba.



## Ha Kini Eleyi




OGUN A PA YANMU—YANMU
OLORI ERIN MẸTA

Three Elephant Brand mosquito coils dara pupọ A ni O dara jul gbogbo ogun a pa yanmuyanmu yoku lọ,

O npa yanmuyanmu ninu ile ni kiakia orun rẹ si dara pupọ ju gbogbo ogun yanmuyanmu yoku lọ. Bakanna ni o si tun yara pa ayan ati idun,

Tete lọ ra packet ogun yanmuyanmu, Three Elephant Brand coils tirẹ loni, ki o si danwo; iwọ y o ri bi o tiṣe pa gbogbo yanmuyanmu inu ile rẹ ti iwọ ati awọn ọmọ rẹ yio si sun daradara

Ki o ri daju pe ogun yanmuyanmu ori erin mẹta ni nwọn mu fun ọ

Three Elephant mosquito Brand coils yi wa ni ṣọbu ls itaja kakiri orilẹ ede yi

Distributor
AMOS GBENLE & BROTHERS
34: Docemo Street Lagos.
6 & 11 Balogun Street West

# IWADI IṢẸ IṢỌWO ATI IMỌ - ẸKỌ IJINLẸ

P. AGUE Ni ọjọ Abamẹta ti iṣe ọjọ kokandinlogun oṣu yi ni irohin kan de si ile iṣẹ wa ati ile iṣẹ aṣoju Ijọba orilẹ ede ilẹ Czechoslovakia ni Naijiria pe, Ijọba orilẹ ede na ti ṣi ile iṣẹ kan ni ilu eyiti iṣe olu ilu fun ilẹ Czechoslovakia ni Prague nibiti gbogbo awọn enia yio ma be ti ma a woran.

Ninu ile ti Ijọba ṣẹṣẹ kọ na, gbogbo awọn enia ni nwọn nlọ woran ninu ile ago ipatẹ ọja agbaiye ti nwọn ko si inu ilu na nisisiyi.

A gbọ pe ninu ile na gbo gbo awọn nkan oriṣiriṣi ti nwọn nṣe ninu ilu na ti nwọn nfi owo wọn ṣe gẹgẹ bi awọn nkan ti wọn ti nko wa lati ilẹ okere si ilu naa lẹ ni nwọn ti bẹrẹsi ma ṣe funrawọn bayi.

Ọkan ninu awọn nkan ti nwọn kojọ si inu ile iṣẹ na ni awọn aṣọ wiwulu ti nwọn nṣe ni orilẹ ede na. Irohin fi ye wa pe, gbogbo awọn enia ti nwọn ba de inu ile ago ipatẹ ọja agbaiye nibiti nwọn ko awọn nkan na pamọ si, won ni nwọn ngbe Ọ oruọ l'Ọga.

Lati Igbana ni awọn enia lati ilẹ okere ti bẹrẹsi ma a wa wo awọn ohun ti nwọn nṣe nibẹ.

Nigbayi ni awọn enia na to le mọ pe, awọn enia inu ilu na le da nkan ṣe funrawọn laikosi iranlọwọ awọn enia orilẹ ede ajeji kankan.

Nigbati nwọn ṣe awọn aṣọ na tan ti nwọn si to wọn si ara ogiri loke fun awọn enia lati maa ri a gbọ pe gbogbo awọn enia ti won nlo wa iran nibe na ni nwọn ngba dun iṣe owo ti awọn enia na ṣe si be, paapajulo, awọn iṣẹ aṣọ hihun ti awọn enia na ṣe ti nwọn ko kọ soke nibe.

A gbọ pe ninu ilu na ni nwon ti ntoju awọn owu ti nwon fi nhun aṣọ na, ero ti nwon si fi nhun aṣọ na awọn enia inu ilu na ni nwon ṣe gbogbo rẹ patapata lati ibere titi de opin

Nigbati nwọn ba pari gbogbo aṣọ hihun na tan, awọn enia na ni nwon nran aṣọ na ni oriṣiriṣi ona ti nwon ba le ran an, ni ba miran nwon fi nran aṣọ okunrin, obinrin, omode ati agbalagba pe lu fun awon enia lati ma lo ra iru eyiti olukuluku enia ba nfe lati ra nigbati nwon ba ti pari won tan.

Ni Ipari, irohin na so pe ko ti si eniti o de inu ile ise owo na ti ko ti kan saara si ohunti Ijọba ṣe ati iṣe ti awọn enia ti nwọn wa nibi iṣe na nṣe.

Ọpọlọpọ awọn orilẹ ede ni won ti nranṣẹ lo ra nkan ninu ilu na Czechoslovakia ti awon na si nlo ni ilu won

## YE IRAWO RE WO

AQUARIUS (Jan 22 Feb 20) Lorito ati lododun ohun ti o fi Iṣiwaju rẹ wa ni Igbiyanju ti o gbiyanju ṣugbọn ile rẹ si tun kun ni ibomiran Iwọ sa ti fi ọgbọn gbe ninu ile rẹ ọrọ yio yanju.

PISCES (Feb 31 Mar 20) Alafia yio de si ọ ara rẹ yio si le gidi tobẹ ti wọ yio ni itẹlọrun lọna gbogbo, larin ile ọrẹ ti ẹbi, bi o ba si ri ọna titun ti enia le fi ba wọ o, ma jafara,

ARIES (Mar 21 April 20) Maṣe da iṣẹ rẹ ru ma si ṣe jẹki o pa ọ laiya o san ki o kuku din iṣẹ ti o nṣe lojọ ku ki arẹ ma ba mu ọ ki gbogbo iṣẹ rẹ ma ba daru.

TAURUS (April 21 May 20) Arẹ fẹ mu ọ, ṣugbọn o yẹ ki o le gba ara rẹ silẹ o si yẹ ki o lọ fi ara lolẹ.

GEMINI (May 21 June 21) Ọjọ on dara, ero ọkan re si dara pẹlu, ṣugbọn inawo airotẹlẹ yio da si o. akoko aṣalẹ yio si mirọrun gidi fun ọ. Iwo yio si gbadun awon alejo ti o wa ki o.

CANCER (June 22 July 22) Iṣẹ ti o fẹ ṣe loni yio pọ arẹ ni yio si pẹkun rẹ fun ọ, di awọn iṣẹ ti o nṣe duro ki o si lo fi ara lelẹ.

LEO (July 23 Aug 22) Iwo ko ni ayaya si enia nitori ki o fi ara mọ ohunkohun ti o nṣe ba pe ṣugbon ki o maṣe omota,

VIRGO (Aug 22Sept 23) igbẹhin ohunti o ṣe silẹ yio dara, Iwọ yio si ri iranlọwọ rẹpẹtẹ.

LIBRA (Aug 24 Oct 23) Gba ara rẹ kuro lọwọ amodi ti o nfẹ je ọ, ibẹsibẹ ile inọ fun ọ to Iwọ yio ri nkan iyanu lati ọdọ awọn ọrẹ ati ẹbi rẹ wa.

SCORPIO (Oct 24 Nov 22) Bọya o le ṣe akiyesi ṣe suru ki o si jẹki o ye o pe ko ni re ka kuro.

SAGITTARIUS (Nov 23 Dec 21) Ṣọra nipa egbo gi ki o ma ba di ọ lamọ pupọ

CAPRICORN (Dec 22 Jan 21) Awọn enia tere ni iwọ yio ba lo pọ loni awọn yio si ṣe iranlọwọ ohunti o nfẹ fun ọ.

## IWE KOṢEMANI NI EYI

IWE ITỌSẸ OHUN GBOGBO
INU ODU MẸRINDINLOGUN

Iwe yi kun fun Asọtẹlẹ ati wipe, yio din ọ lowo YẸMIWO" ku, nitoripe iwọ na yio le ma da ṣe AYẸWO fun ara rẹ
KOṢEMANI" ni Iwe na, 2/6d pere ni a ntai-
Postage 9d
ẸSAN KOGBOGUN SERVICE
8, Idumagbo Avenue
Lagos Nigeria (Leti Ọja Jankara)


a successful future
means planning *Now!*

Have you planned for the security of your family's future? Start a programme of Life Insurance NOW

*with*

**GREAT NIGERIA INSURANCE Co. Ltd.,**
INCORPORATED IN NIGERIA

Enquire now for full details of our low cost endowment policy.

HEAD OFFICE:

39/41 MARTINS STREET,
P.O. Box 2314, LAGOS
TELEPHONE 25251

BRANCHES AND AGENTS THROUGHOUT NIGERIA


# E Ma Ka Iwe Irohin Imọlẹ

# AWỌN ALAGBẸDẸ KESI ỌGAGUN FAJUYI

SHAGAMU:— Ninu iroh'n kan to de ile i ṣ ẹ wa ni Kutukutu owurọ ọjọ Iṣẹgun ti Iṣe ọjọ kejilelogun oṣu yi lati ọwọ Oniwe irohin wa ni ẹkun Ijẹbu Rẹmọ ni o ti ṣe alaye ninu irohin rẹ pe awọn Alagbẹdẹ ti nw n nṣe ibọn Ṣakabula to wa ni ẹkun Ijẹbu-Rẹmọ ti kesi Gomina Ologun Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria lati si Ofin ti Ijọba fi de awọn Alagbẹdẹ to nṣe ibọn Ṣakabula ati a w ọ n Ọl. dẹ ẹkun na lati le jẹki nwọn ma lo ni jakejado ẹkun Ijẹbu—Rẹmọ.

Ninu ipade kan ti awọn ẹgbẹ Alagbẹdẹ to nṣe ibọn Ṣakabula ni ẹkun I j ẹ b u Rẹmọ ni Akọwe agba ẹgbẹ na Ọgbẹni Samuel Oni ti ṣe alaye ninu ipade pa jawiri ti a w ọ n ọ m ọ gbẹ na ṣe ni ilu Shagamu ni opin ọsẹ to koja pe lati igbati Ijọba ti ofin de pe nwọn ko gbọdọ ri ibọn sa kabula ni ta, o jẹ ohunti o soro pupọ fun aw n ẹgbẹ wọn lati ri enia ti yio ra awọn ibọn ti nwọn nṣe ati pe ko si fun ẹgbẹ wọn lati ma ra awon ibọn na mọ

Ogbẹni Oni tun ṣe alaye pe eleyi jẹ ohunti o soro fun awon omo ẹgbẹ Alagbẹ dẹ ti nwon ma arọ ibọn lati ri ọna ti nwọn yio ti ṣe ri onjẹ oojọ awọn ati pe iṣẹ ibọn riro ti awon nṣe ni awọn ngba ri onjẹ je.

Ogbẹni Samuel Oni tun ṣe alaye ninu iwe ti nwon ko si Ogagun Adekunle Fajuyi pe gbogbo ibọn ti awọn ti ṣe silẹ fun tita ati awon eyiti nwọn ko ti ṣe pari ni awon ti ko fun awon Olopa nigbati nwon ti ṣe ikede ninu opin odun to koja pe nwon ko gbọ do ri ibon ninu ile ẹnikẹ ni ati pe o jẹ ohunti o lo di si ofin Ijola

Awọn ẹgbẹ na tun ṣe alaye ninu iwe ẹbẹ ti nwọn ko si Gomina Ologun Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria Ọgagun Adekunle Fajuyi ni nwọn ti ṣe alaye pe yio dara bi Ijọba Ologun ba le ṣe ofin lati jẹki awọn ti nṣe ibọn ṣakabula na ki nwọn ma gba iwe aṣẹ ki nwọn to le ma ṣe ibọn na ni Ipinle na.

Akọwe awọn Alagbede to nṣe ibọn na tun ṣe alaye pe a w ọ n egbe on tiṣe tan lati faramọ ofin yowu ti Gomina Ologun Ipinlẹ na ba le ṣe lori ibọn sakabula lati le fun awọn laye lati ma rọ ibọn na ta ti egbe on ko ni salai fi ara mọ lori eto ofin nipa iwe aṣẹ ti awọn ni lati ma gba ki nwọn to le maṣe ibọn na

Ni ipari awọn ẹgbẹ na tun ṣe alaye ninu iwe ti nwọn kọ si Gomina Ologun Ipinlẹ na pe ọna ti awọn ngba ri onjẹ oojọ awọn jẹ ni ọna iṣẹ ọwọ ẹwọn ti awọn nṣe eyiti o je ibọn riro atipe inu awọn yio dun bi ọna ba le si sile fun awọn lati ma rọ ibọn awọn ta ki nwọn si se ayipada ofin na eyi ti awọn yio fi ni anfani lati gbe awọn ibọn wọn pada lọgba awọn Ọlọpa


GBOGBO ARA ILU NKỌ ORIN IYIN ATI OGO NIPA DYNAMIREN TỌNIKI

ALE-IBI-ALE Egbogi Tọ ki amọnu, titun ti gbogbo ara Ilu Eko ati jakejado Naijiria mọ ọ̀ọ̀ ilu Agbara ati Ajẹbidan ṣẹ iira agbalagba Ọkunrin ati Obinrin gbogbo



Bi arẹ ara ba nmu ọ, ni gbakugba fun wahala tabi iṣẹ ṣiṣe ti o ko le jẹun dara dara, tabi ki o male sun da da de ọkan lọsan tabi awọn ṣan ara rẹ gbogbo ki ṣe fun daradara ti Emi Breath inu ko ba kunlẹ daradara wọn iṣẹ tabi wahala sise tabi inu awọn ailera gbogbo ayin ti ọjọ ori (age) ba ti kọja ogbọn ọdun si adọrin tabi jubẹ lọ mọ daju pe DYNA MIREN ni egbogi ti o nfẹ lati sọ ara rẹ di ọtunp pata oju rẹ yio si walẹ re kete alafia ati igbadun de Bere Dynamiren yi ni Ṣọbu awọn i-

Waterloo Medicine Stores
8 PalmChurch Street Lagos
22878 Lagos Nigeria (Ọja Ita Faaji)
LAGOS ISLAND CHEMIST
Nnamdi Azikiwe Street, Lagos
UNITED DRUG CHEMIST
Alli Street, Lagos.
ATI NI ṢỌBU
IṢE OLODUMARE DISPENSARY OKE BỌLA
IBADAN



## KERE O

Njẹ o ti ni ninu "IWE ITAN ODUDUWA ọsẹ ṣẹjade ?

Ha ! Kosemani ni Iwe na jẹ fun ọmọ Yoruba Iwe na kun fun itan Iṣẹdalẹ Yoruba, Kedere ni aworan Oduduwa ati ti ọmọ rẹ han ninu rẹ.

Mase jẹki nwọn rohin itan ilu rẹ fun ọ
3/- pere ni. Postage 9d

Tete fowo tirẹ ranṣẹ si:-

ẸSAN KOGBOGUN SERVICE
8 Idumagbo Avenue Lagos Nigeria



## Iwe Itaja 1966

Idamu owo ha wa fun ọ bi
Abiku ha nyọ ọ lẹnu bi
Airi iṣẹ se ha wa fun ọ bi
Ailera mba ọ ja bi
?

Iwọ le bọ ninu gbogbo wahala aiye wọnyi ti i ọ ba ra ninu awọn ohun Ijinlẹ Iṣẹdalẹ Yoruba ti a to lesẹsẹ si Isalẹ yi.

1 Iwe Egbogi Ajẹbidan 25/— di 22/6
2 Iwe Afọsẹ Iṣẹdalẹ Yoruba ati Psalm Ajẹbidan 4/6 di 3/6
3 Iwe Itumọ Ala ati Ogun Wibẹjẹbẹ 4/6 di 3/6
4 Iwe Egbogi Awogba Arun 20/— di 17/6
5 Iwe Ilana Ifa Yanrin tite ati etutu ṣiṣe 20/- di 17/6
6 Gbedegbẹyọ Hausa 3/—
7 Iwe Aniyan Irun 2/— di 1/—
8 Turari Iṣẹgun Ajẹ ati Itaja 10/6 Pangolo 2/6 paketi

Fi Owo ranṣẹ si
J, O, SHOYINKA
P, O, Box 159
MUSHIN
tabi
9, Iyala Street Oduabọrẹ, Mushin

# IROHIN IMỌLẸ

IMỌLẸ ỌRẸ AIYE TẸNI GBOGBO LAWA

NO 1,705 WEDNESDAY FEBRUARY 23 1966 (2D)


## Enia Meje Ku Ninu Ijamba Mọto

OTURKPO:- Ni opin ọsẹ to kọja lọ yi ni ijamba mọto kan ṣẹlẹ ni oju ọna Oturkpo si Bọju Ipinlẹ Ila Orun Naijiria eyiti awọn enia meje ti ọmọde jojolo kan ti iṣe mọ ọsẹ mọkanla si pelu awọn enia to ku lẹsẹkẹsẹ nigbati ijamba mọto akero na ṣẹlẹ ti enia marundinlogoji si tun fi ara gbọgbẹ ninu ijamba mọto to ṣẹlẹ na.

Irohin fi ye wa pe mọto akero na si nlọ si ilu Weto lọ si Oturkpo sugbọn enia mẹta ninu awọn to fi ara gbẹgbẹ ninu ijamba mọto na ni ẹmi wọn si wa ninu ewu ninu ile Iwosan Oturkpo bayi.

Eleyi ni orukọ awọn enia meje to ku lẹsẹkẹsẹ ti ijamba mọto na ṣẹlẹ ni ọjọ na awọn ni Alikun Acheme, Agbo, Ogbu, Audu Adejo, Zakari Eba, malam Yerima, Ene, gbede ati ọmọde jojolo ti iṣe ọmọ osu mọkanla.

Oniwe irohin wa to lọ sibi ti iṣẹlẹ na ti ṣẹlẹ fi ye wa ninu irohin rẹ pe awọn ọlọpa ti Ijọba ibilẹ ti ilu Idoma ti mu Dirẹba mọto na eyiti orukọ Dirẹba na njẹ Godwin Ogwu ati pe awọn ọlọpa na ti bẹrẹsi ṣe iwadi ohunti o fa ijamba mọto na wa.

Bakanna ni awọn ọlọpa nṣe iwadi lori ohunti o fa Ijamba mọto na wa Irohin tun fi ye wa pe ile iwosan lakulaku ni nwọn gbe oku enia meje to ku ninu Ijamba mọto na.

# AWỌN ENIA ILU ỌWỌ FẸ RỌ ỌBA OLỌWO LOYE

ỌWỌ:— Ninu Irohin kan to de ile iṣẹ wa ni deede agogo kan ọsan ọjọ Aje ti iṣe ọjọ kọkanlelogun oṣu yi ni irohin na ti fi ye wa lati ilu Ọwọ pe awọn enia ilu na ti kọwe ẹbẹ si Gomina Ologun Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria Ọgagun Francis Adekunle Fajuyi lati lo ipo rẹ rere lati le jẹki awọn enia ilu Ọwọ yan Ọba ọlọwọ ti ilu Owọ ti o si jẹ ọkan ninu Ọba ilẹ Yoruba ki so pẹlu awọn ọba to wa ninu igbimọ awọn Ọba fun Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria.

Oniwe irohin wa kan to wa ni ilu Ọwọ fi ye wa ni na irohin re pe awon ọmọ ibile ilu Ọwọ ti nwọn kun fun ayọ ijo, ti nwọn si ngmu ọti bi ẹnipe omi ni nwọn si tun nse ti nwọ nsọ fun onjẹ nigbati Gomina Ologun Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria ṣe ikede awon oba Ipinlẹ Iwo Orun ti Ijoba Ologun na yan sinu Igbimọ awon oba fun ijoba Ipinle na eyiti awon omo ibile ilu Owo si ndun nipa pe Gomina Ologun na ko yan oba Olagbeji keji Ọlọwọ ti ilu Owọ sinu Igbimọ na.

Awọn ọmọ ibilẹ ilu Owo na tun kesi Gomina Ologun Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria lati tete rọ ọba Olatẹru Olagbeji keji Ọlọwọ ilu Owo loye ki nwọn yan enia ti o jẹ wipe awọn ọmọ ibilẹ ilu na faramọ lati wa lori oye gẹgẹbi ọba ilu Ọwọ ti yio ṣ ni anfani lati pẹlu Igbimọ awọn ọba Ipinlẹ na gẹgẹbi awọn ọba yoku.

Awọn ọmọ ibilẹ ilu Ọwọ na tun kesi Gomina Ologun Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria Ọgagun Adekunle Fajuyi lati tete lo ipo rẹ rere ki awọn si yan Ọba titun ti yio si ni anfani lati jẹ ọkan ninu awọn Igbimọ Ọba fun Ipinle Iwọ Orun eyiti Ọba ọlọwọ si jẹ ọkan ninu igbimọ awon Ọba tẹle ri fun Ijoba Ipinlẹ Iwo Orun Naijiria:

Oniwe Irohin wa kan tan wa leti pe ni ọsẹ to koja lo yi ni Ijoba Ologun Ipinlẹ Iwo Orun Naijiria yan awọn Ọba mokan'la pataki ni Ipinlẹ Iwo Orun Naijiria lati wa ni ninu Igbimo awon Ọba fun Ijoba Ipinlẹ na eyiti Ọba Alaiyeluwa Adesoji Aderẹmi Ọọni ti ilu Ile Ifẹ gẹgẹbi olori awọn ọba fun Igbimọ awọn ọba Ipinlẹ na ti Ijọba Ologun na tun yan Bello Gbadegerin Ladigbolu, Alafin ti ilu Ọyọ gẹgẹbi igbakeji Olori Igbimọ awọn ọba Ipinlẹ na.

Ninu awọn ọba ti Ijọba Ologun ti Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria yan lasiko na ni Alake ti ilu Abẹokuta. Awujale ti ilẹ Ijẹbu, Ọwa ti ilu Ilesha' Ọragun ti ilia Deji ti ilu Akurẹ, Osemawe ti ilu Ondo, Akarigbo o Ijẹbu Rẹmọ Lwa ti ilu Ado Ekiti ati Olubadan ti ilu Ibadan

Oniwe Irohin wa kan tan wa leti pe ọba Ologbegi keji Ọlọwọ ti ilu Owọ io ti kọkọ wa gẹgẹbi Olori ile Igbimọ awon ọba ati Loye fun Ijoba Ipinlẹ Iwo Orun tẹlẹ ri ki awọn ọmọ ogun to gba Ijoba Ipo na ni o jẹ pe ọba Ọọni ti ilu Ile Ifẹ lo si nwa oye Olori ile igbimo na tẹlẹ

# Minista Marun Lati Oju Ewe Kini

Alamojuto eto Igbokegbodo ọkọ fun Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun tẹlẹ fi ara han ni olu ile iṣẹ awọn Ọlopa nu ti ilu Ibadan lori ẹsun kan to awọn awọn Ọlopa taku lati fi ye oniwe Irohin wa,

Oniwe Irohin kan tun ṣe alaye fun wa pe ohunti awọn ọlọpa nu ṣe mu awon enia na ninu ọsẹ to kọja lọ yi ni ẹsun ole ti Ijọba Ologun ti Ipinlẹ Iwọ Orun fi kan wọn pe nwọn jale Ijọba ati pe nwon ji owo Ijoba Ipinlẹ na gbe.

Irohin tun fi ye wa pe awọn ẹlomiran si tun wa ti Ijọba Ologun Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria yio si tun fi ẹsun ole kan pe nwọn ji owo Ijọba Ipinlẹ na gbe tabi pe awọn enia na ninu awọn ẹgbẹ oṣelu ati Minista fun Ijọba Ipinlẹ tẹlẹ ni Ijọba Ologun yio fi ẹsun na kan laipẹ yi

Ni ojo Iṣẹgun ti iṣe ọjọ kẹjọ osu ti mbọ ni Adaju ile ẹjọ ... Sikiru Ayinla Abina yio ma gbo ẹjọ Adajọ na si pa sẹ ... ko awọn Minista na lo pamọ si ọgba ẹwọn Agodi Ibadan

Bakanna ni Irohin tun de ile iṣẹ wa ni ọsan ana ọjọ iṣẹgun ti Iṣe ojo kejilelogun oṣu yi pe Gomina Ologun Ipinlẹ Iwo Orun Naijiria Ọgagun Adekunle Fajuyi ti pase pe ki nwon da oga agba ti nṣe eto akoso awon Ẹlawọn ni ogba ẹwọn ti Agodi Ọgbeni D. W Aiyedun ati Igbakeji re Ọgbeni E O Ogunkanmi duro lenu iṣe won gegebi oga ati Igbakeji oga awon Alakoso Ẹleri Agodi Ibadan

Nino esun ti Gomina Ologun fi Ijoba Ipinle na fi kan awon Alakoso Ẹlẹwon ti Agodi Ibadan meji na ni pe awon enia meji na kuna lati tele aṣẹ ti Ijaba Ologun Ipinle Iwo Orun Naijiria pa fun won lori awọn Minista fun Ijọba Ipinle Iwọ Orun ati awọn Alakoso ile iṣẹ ti Ijọba paṣẹ pe ki nwọn lo fi pamọ si ogba ẹwọn Irohin fi ye wa pe awọn Alamoto awọn Ẹlẹwọn meji na kana lati tẹlẹ aṣẹ ti Ijọba Ologun pa fun wọn iṣẹ awọn enia na ti pari ni ọjọ Iṣẹgun ti iṣe ọjọ kejilelogun oṣu yi.


Printed and Published By Modupe Printing Press 16, Gbangbose Street, Lagos Phone 21985
Editor: TUNJI ADEOSUN 25 Branco Street Lagos 22/2/66